# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 909 LAGOS SATURDAY FEB 22 — FEB 28 1984 KOBO MEJI (D)

## ORO BEHIN YO!

# Ara Olowogbowo Keran, Ijọba Ni Ko Si Ile, Owo Ni Nwon Yio Gba

EKO — Ọpọlọpọ awọn akọwe-ile ni Ijọba ti gbe jade wipe ki nwọn ma ka gbogbo awọn enia ti nwọn ngbe inu awọn ile ti nwọn fẹ gba lọwọ awọn ara Olowogbowo kiri, ki awọn le ma iye owo ti Ijọba yio san lori gbogbo awọn ile ti nwọn fẹ gba na.

Gẹgẹbi irohin ti awa Eleti-Ọfẹ gbe jade ni iwọn oṣu 'kan sẹhin wipe Ijọba fẹ ko awọn ara Olowogbowo lọ si Okun Alasia nitori kereni tuntun ti nwọn fẹ ṣe lati ọna Ọjọra, a gbọ ninu iwe ikede ti Ijọba (gazette) wipe Ijọba ko ni fun ẹnikan ni ile ti awọn yio gbe dipo ile ti Ijọba yio gba, awọn ni owo ni awọn yio san fun awọn ẹbi ti nwọn ba 'gba ile wọn.

A gbọ wipe o le ni igba agbole ti Ijọba yio wa danu ni Opopo Apọngbọn, Johnson, Itọlọ, Arimashaun, Ọdọfin, Amosun, Ebute Alakoro, Be eku Idita, Alapafuja ati Aibu; ọpọlọpọ awọn ara adugbo wọnyi ni awọn akowe ile ti Ijọba yan si ita si ti nkan lara lati ijọ ti wa.

Gẹgẹbi ofin ile gbigba, Ijọba ni ẹnikẹni ko gbọ o di ẹnikẹni ti awọn ba ran wipe ki nwọn wa wo awọn ile na lọ o, ẹnikẹni ti o si r wipe on lẹtọ si ile ti nwọn fẹ wo ki o kọwe ranṣẹ si Minisita lamojuto eto ilu Eko, Alhaji Musa Yaar'Adua nibi ile iṣẹ rẹ nilu Eko larin ọsẹ mefa.

Ijọbo ni awọn ẹbi ti ko ba tete kọwe si awọn larin oṣu kan ati ati abọ lori ile wọn ti nwọn lẹ wo na, awọn ko ni gbọrọ wọn mọ.

Ogunlọgọ awọn lọya (agbẹjọro) ni a gbọ wipe nwọn ti nfẹ palẹ ile ẹbi awọn ara Olowogbowo ti awọn fẹ gba ile wọn boya nwọn le ri ibi kan ba wọ ọ lọdọ wọn



Alhaji MUSA YAR'ADUA

## Ejo Kotemilorun Awolowo Ku Ferefe Ni Kotu

EKO—Irohin kan ti a tun gbọ ni ẹnu awọn akọwe kotu giga l'Ọfin ni owurọ ana ni wipe awọn lọya kan ti fi iwe ranṣẹ si ile-kotu wipe ki nwọn tete gbọ ẹjọ kotemilorun ti Oloye Ọbafemi Awolọwọ ti nwọn fi sẹwọn lori ọrọ ote ti nwọn di wipe nwọn sọba pe, wipe awọn fẹ ki awọn adajọ tete gbọ ẹjọ na; ni owurọ ọjunla ni nwọn yio gbọ okan ti awọn lọya na fẹ sọ nipa wipe ki nwọn tete gbọ ẹjọ kotemilọrun na.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, a gbọ wipe ẹgbẹta pọnun (£600) ni owo ti Oloye Awolọwọ san si kotu lati fi ra ẹda iwe gbogbo ẹjọ ti nwọn ro nigbati nwọn mba wọn ro ẹjọ ni Kotu lẹsin.

(Wo yoku loju ewe lẹjọ)



Oloye OBAFEMI AWOLOWO

## AYILUKA NI:

### ARA OLOWOGBOWO KERAN

Ọrọ ile ti Ijọba fẹ gba ni Olowogbowo mọ Ebute Alakoro ko arẹ ọkan ba mi pupọ nitoripe Olowogbowo yi ni mo ba wọn ṣe ọmọde nigba atijọ, ti mo ba si nwo adugbo bi Itọlọ, Alakoro, Johnson, Alapafuja, Apọngbọ ati Ọfin, mo mọ niran gbogbo awọn ẹbi patakipataki ti temi pelu ọmọ wọn ti jọ ṣere pọ

(Wo yoku loju ewe lẹjọ)

# British City's Gift For Nigerian Flying Doctor Service

LONDON – The Flying Doctor Service of Nigeria has reached a "turning point" in its fortunes and it is now fairly certain that flying will start in April. This is what the doctor's wife, Mrs Duncan, told the Plymouth Branch of the International Friendship League in southern England last weeked, when receiving a cheque for £290 to buy a radio for the village of Kaingiwa, in Northern Nigeria.

The Plymouth Branch has "adopted" the village and the cheque was presented by its President, Mr. Ritchie Symons,

"I am happy and proud to be making this presentation, It was a delight to raise the money for something which helps the sick he said.

Accopting the cheque, Mrs Duncan said she "new what pleasure the gift would give in Nigeria. She went on: 'Thank you for your generosity and for your personal interest. We are powerless without the help of people like yourselves,

Explaining tha the radio would enable the dispenser at Kaingiwa to get expert medical advice on the treatment of his patients, she promised to keep the Plymouth Branch of the League in touch with developments.

The Nigerian chairman of the Plymouth Branch, Mr Frank Aoyamene from Onitsha, who is studying civil engineering in Britoin told an L.D.S. correspondent he understood and appreciated the effects which the Flying Doctor Service could have in Nigeria.

The Service, launched in Nigeria by Dr. Neil Duncan of Birmingham, is sponsored in Britain by the "Freedom from Hunger" organisation: Campaigning all over the country by local organisers and youth groups has so far raised a total of over £55,000 for the Service which will also carry agricultural and veterinary services to remote districts.

Some of these funds have been ear-marked towards a new plane to replace one bought with O.XF.A.M. funds which was damaged by storm in Nigeria and a second, damaged before reaching Nigeria.

Now a new gift has come from Switzerland to make up the balance-£6,500 from the Swiss drug firm of Geigy.

## Indiscriminate Arrests In Kashmir

NEW DELHI...Indiscriminate arrests are being made in Srinagar, Baramula and from other places in the Valley, according to a diplomatic informant here.

The new flare-up of popular revolt began on Friday the 24th January, when thousands prayed and wept in Srinagar, Jama Masjid, a Grand Mosque, lamenting the loss of the Prophet's holy hair.

Fearing that the congregation might demonstrate in the city, Indian Armed Police brought in from Rajasthan blocked their path and forced them into by-lanes. Several people were beaten and at least two received bayonet wotunds, though not serious

## Pakistan To Buy Four Ships From Yugoslavia

RAWALPINDI–Pakistan would shortly buy four ships form Yugoslavia, which had been offered on credit.

Deputy Chairman of the Planning Commission, Mr. Said Hasan, told newsmen today that Pakistan had already signed an agreement with Yugoslavia for buying two ships, out of dollar five million loan.

Another agreement for buying two more ships was ready to be signed, under which Yugoslavia would exted a dollar five millieu loan to Pakistan.


*Available!*

Choose your Mercedes-Benz 220s NOW.

A rich variety of colours is at last available.

MERCEDES-BENZ 220s



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

Iwe Akoka Yoruba

# Ayo Ominira Nigeria

Lati Owo Atilade

Kini Lamọrin yio ṣe?
Bi ti ọmọ enia kọ,
Enia t'Ọlọrun ti l'ehin,
Ama ṣe gudugudu meje l'ogun,
A si ma p'ayo mẹfa lọdẹdẹ:
Ẹ ba mi gbe 'di fun Lugard,
Ọkunrin ọlọgbọn, ọkunrin ologun,
T'o wo asia Ẹgbẹ Royal Niger palẹ,
T' o si gbe ti Ijọba Gẹsi ro.
Ọgbọn ki iṣe ẹgbẹ ọgbọn
Imọ ki iṣe ẹgbẹ imọ,
Agbara ju agbara lọ,
Ẹ ba mi bẹri fun Lugard;
Baba onikalamu ibọn, onimẹran ida,
T'o f' ikuku jakunmọ ka ehin ikoko,
T'o f' ekanna awodi tu ifuu aṣa;
O ni ere ni ẹiyẹ mb'ẹyẹ ṣe;
Họwu! Ere ni ẹiyẹ mb'ẹiyẹ ṣe
Ni a atu ifuu ara ẹni?
O f'ọgbọn so 'run 'waju,
Pọ mọ t' ipakọ;
O f'olu bomba
Wo oje pọ mọ baba;
O mu Yoruba 'Wọ Orun

(Wo iyoku loju ewe kẹfa)

# New Com[illegible] Of Elder [illegible]pster

LONDON — The British [illegible] Elder D[illegible]pster Lines Ltd., whose sh[illegible] Brita[illegible] and West Africa, have [illegible] the app[illegible] Captain T.I..M. Jenkins a[illegible] of the F[illegible]

Commodore Jenkins was in command of m.v. AUROL when President and Mrs Tubman returned to Liberia following their State Visit to Britain in 1962 The President later honoured him with the decoration of [illegible]

Commodore Jenkins is at present in command of m.v. EBUE which sailed to West Africa [illegible] last week for Dakar, Apapa, Victoria and Port Harcourt.

# Oseni Fi Igba Ponun Su "Taba" Lodo Ijoba

IBADAN - Gbogbo awọn enia ti nwọn wa si Kotu Onireke ni nwọn bu si ẹrin gbaa nigbati arufin kan, Oseni Adisa, ti awọn ọlọpa gba mu wipe awọn ka ewe taba igbo mọ lọwọ, nigbati o nṣe alaye ọrọ na fun adajọ ti o ni ki o fi igba pọnun tanran tabi ki o lọ ṣẹwọn ọdun meji pẹlu iṣẹ aṣe kara.

Oseni ni ntotọ ni nwọn ba "igbo" lọwọ on, ko le se ki on ma mu u mọ nitoripe ewe igbo yi ni on fi nṣe ara nigbati gbogbo nkan ti baje ni Ibadan ti iṣẹ ko si mọ fun ọkunrin ati fun obinrin.

Bi nwọn ti nṣe ẹjọ Oseni yi lọwọ ni awọn Ọlọpa Eko tun gba obinrin Ibo kan mu ni Abule Amukoko, l'Ọjọra Oloye pẹlu ewe taba igbo ti wọn nba ninuiyara rẹ; Angelina Ogbomọdu ni nwọn pe oruko obinrin arufin na.

Awọn ọlọpa ni ti nwọn ba fẹ ti ewe igbo ti nwọn ba lọwọ obinrin na owo ti nwọn a ri a to adọta lerugba pọnun (£250).

Obinrin arufin na bẹ adajọ wipe ki o darijinn on, on ko ni ṣe bẹ mọ: Ju gbogbo rẹ lọ, adajọ ni ki o lọ fi adọjọ pọnun tanran tabi ki o lọ ṣẹwọn ọdun kan gbako

BP PASS ALL! - BP PASS ALL! - BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ
BP SUPERLITE
KEROSINE
L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri ra nibikibi, ko si wẹrẹ, o mọ dandan, owun lo si dara ju fun ounje-sise, ina-titan ati lati ma fi yiná Kerosine ti o dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

ELETI-OFE
(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)
EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos, B. O. Box 467
CABLE & TELEGRAME "ELETI-ỌFẸ" LAGOS Phone 23370
VOL XIV. NO 909 SATURDAY Feb. 22 - Feb. 28 1964.

ORO OLOTU:

# Bi Ko Ba Si Iku Ile....

Awọn agbalagba Yoruba ni owe fun orişirişi nkan ti o ba de ba wọn, ko ba jẹ nkan ayọ tabi nkan ibanuje ni; nwọn ni BI KO BA SI IKU NILE T'ODE KO LE PA NI. Nitotọ ni, ọrọ awọn ọlọşa danadana ti nwọn wọ aşọ kaba awọn obinrin lọ si ile işẹ awọn onipuru ni Apapa loru lati ko owo ti nwọn pa ni o mu ọrọ olotu wa ti ọsẹ yi wa.

Ọpọlọpọ igba ni a ti ma nşe alaye fun awọn alamojuto Ijọba wa wipe awọn Ọlọpa wa ko mojuto işẹ ti nwọn gba wọn to, nşe ni nwọn nfi ẹtẹ silẹ ti nwọn npa lapalapa.

## T'ode Ko Lẹ Pani

Ni Ajeguulẹ ni Apapa teşan awọn ọlọpa wa nibẹ ati ni Ebute Mẹta pẹlu. A gbọ wipe o to ọsẹ melo kan ti awọn ọga işẹ pulu yi ti mbẹbẹ wipe awọn fẹ Ọlọpa fun abo ibi işẹ awọn nigbati nwọn ti nşe akiyesi bi nkan ti nlọ si ti awọn kan npara ọdọ wọn loruloru. Şugbọn awọn ọga ọlọpa yi ko mu ogiri si ọrọ wọn titi o fi di wipe awọn ọlọşa na fi gbe mọto wa gbe won lowo lọ.

Irufẹ iwa wo ni ẹ mọ eyi si? Ọlọpa njẹ nibikibi; nwọn ko ise wipe awọn fẹ ọlọpa abo nitori awọn ọlọşa, a tun nsọ wipe ki a şeşẹ iẹni ki a mọ ro ẹjọ lori rẹ ki a to fun wa lọlọpa. Tani ko mọ wipe iwa amunisilẹ dole ni ọrọ na fẹ jọ.

Şe ẹnyin ara ilu wa ri wipe bi ko ba si iku nile ti ode ko le pa ni. Ọrọ re, ẹnyin ọga ọlọpa!

# Ara Ita Yio Ya a Lofa

Gbogbo awọn alamu ni nwọn dọbalẹ gbọrọgbọ şugbọn a ko mọ eyiti inu nru; ninu ọdun yi ni awọn oşelu wa lọtun ati losi fẹ şe bibẹ lori awa mekuunu ti nwọn fẹ jọba le lori ni gbogbo igun mẹrẹrin ilẹ Nigeria. Olukuluku wọn ni nwọn si npalẹ ogun mọ.

Bi awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti nko ara wọn lọ si Kano lati lọ şe igbaradi bi ẹgbẹ awọn yio se jagun mole, bi awọn ọmọ ẸGBẸ OLOMI (NPC) nfori ni ọdọ olori wọn ni Kaduna, ti nwọn si nşe ileri wipe ẹgbẹ awọn ni yio tukọ Olotu Ijọba ilẹ yi titi lai.

Awa Eleti-Ọfe ko le ko ọrọ yi pada sẹnu awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (NPC) nitori pe onigba ni o

# Iwe Si Olotu

# Dokita Chike Obi Foro Oselu Sile Patapata

OWERRI - Oluko agba kan ninu ilewe giga Ibadan ti orukọ rẹ njẹ Chike obi, ti o tun nşe olori awọn ẹgbẹ oşelu kan, Dynamic Party ni a gbọ ti o sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ wipe bi iwaju ko ba şe lọ ẹhin a şe pada si, on ti şe ipinnu wipe on ko ni ba wọn şe oşelu mọ ti nwọn ba tun fẹ dibo mirau lọtẹ yi.



Dokita Chike Obi

(Wo yoku loju ewe kejọ)

ỌRỌ OLOTU:

npe igba rẹ ni akeragba ti a fi i ba ko ilẹ. A ko si le ri ẹnikan ti yio wipe on ko fẹ ki iyọ ko dun ọbẹ ti on ninu aiye ti a wa yi.

Awọn ẹgbẹ Olomi ni nkankan ni o da awọn loju, iyẹn ni wipe otitọ ti awọn ti nşe fun orilẹ ede yi lati igbati awọn ti gba ominira ni yio tun jẹki awọn bori ninu idibo ti awọn ba tun di lọtẹ yi.

Otitọ ọrọ bi isọkusọ ni o ri ẹnyin na ẹ şe akiyesi bi a ti nşe ilu wa lọjọ oni, kaka ki a wo ibiti arun nperi ti nfẹ wọ ọrọ wa ẹgbẹ ti ko lori, ti ko nidi ni a nda silẹ. Oni a gbọ wipe Yoruba Parapọ, ọla a o tun gbọ wipe Yoruba Poripọ.

Nkankan di a mọ wipe o daju; ẸNITI O BA WIPE KI ARA ile on MỌ LOWO, ARA ITA NI YIO YA A LỌFA. Ara, ẹ kiyesi ara!

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Awa Ni A Ko o

Ẹnyin ara mi, iwọsi wa pupọ ninu ọrọ a nṣelu ni ile yi, nkan ti o je ki emi Ayiluka wi bayi ni ọrọ awọn oṣelu kan ti nwọn fi igba kan fi oruko wọn sọ adugbo ni Ibadan, ti nwọn ni ki nwọn pa gbogbo oruko wọn na rẹ bi ọgan ni gbogbo adugbo ti nwọn gbe kọ ẹ si.

## Lati Owo Ayiluka

Bi emi ba je oṣelu nko ni gba enikan laye wipe ki nwọn fi oruko mi sọ adugbo kan rara ni Nigeria dipo eyi mo le sọ abule ti mo ba da silẹ ni oruko mi tabi ti baba mi tabi ti iya mi.

## Awa Ni A Pare

Mo mọ wipe ko si otẹ ti o le tẹ ti ki nwọn gba ile baba mi tabi oko baba mi. Nkan ti o jeki nsọ ọrọ bayi ni ni irohin kan ti mo gbọ lati Ibadan wipe nwọn pa oruko ep po ti nwọn npe ni Awolọwọ da si ti Balogun Apanpa ati ti Oloye Rotimi Williams pelu Enahoro mo gbọ wipe ọrọ na tun ba oju o p o p o ti nwọn sọ ni Adegbenro wi ỌRỌ NA WA DI A W A NI A kọ AWA NI A PAA RẸ.

Boya orin kan ti awọn Ijesha ma nkọ n i a i y e atijọ bayi ni a le kọ si gbogbo ọrọ na.

Nko si nile,
Nwọn ko iyan m i kere;
nko si lọja;
nwọn pa sọ mi da;
Ara inu ọja bayi ni ẹ nṣe ?



Alhaji D S Adegbenro

Ẹnyin ara ilu Nigeria re bayi ni ẹ se ? En o ba ri ......... ọrọ pọ nibẹ sucho e o oṣelu ẹ ẹ u ej kan sọ oruko ti d rara nitori awọn ti o pa k da d.

Balẹ ti o je ti aiye fi ye w bu ẹ o mọ e; balẹ ti o jẹ ti ilu fọ m ọ tori inu balẹ na ni on na wa.

(Wo iyoku loju ewe kejo)

# E Ma Ka Iwe Irohin ELETI-OFE ni oseose.

# Marsh: Director Of British Management Institute

The Direc of the British Instute of M nageme t, Mr. John Marsh, will address the A nual Co fere-nce of the Nigerian Institute of Management which is being held at the Mainland Hote, Lagos from February 27—29. Mr Marsh will speak on "MANAGE-MENT AS A TOOL FOR INCREASING PRODU CTIVITY" and on "THE ROLE OF AN INSTITUTE OF MANAGEMENT".

He will a so present the Nigeria Institute of Management with a set British books on he art of management. The book are he gift of Britain's Counc for Technical Education and Training for Overseas Countries, of which he is a member.

Mr. Marsh will fl to Kano on February 23 and expects to visit Kaduna and Zar a before journeying to L gos for the Conference. After the Conference he hopes to vst Ibadan. He returns to London on March 3.

## Extensive Experience

Mr. Marsh has carried out extensive lecturing and study tours in urope and other parts of the world. In 1953 he visited India and Pakistan and again visited these countries in 1657 and 1963. He also lectured in Canada and the United States in 1958 and 1960.

Before the war Mr Marsh worked for the Austin Motor C m an , he served from 1939- 946 h he Royal Army Service Corps and hec me pr ner f war in Jap

Dem h ed M he join d BOAC s a personnel officer In 1947 he was appo n ed Director of the Insi tute of Personnel Management and two year later he bec me D rector of the Industr a Welf re Society He held this p st until 1951 hen he t p his p esent appo ntment.

He is at present me ber of the BBC Council and has Honorary Adm of the D ke of Edi 's Study C fere ce man of V Overseas and of the Nationa C fere ce on Social Work.

He has wrote umber of books and on different aspec of the art of management.

# Ogun Ada-ja Be Sile Ni Abisinia

ADDIS ABABA—Lati bi ojo n esan ni awon ara ilu Itopia ati Somalia ti nwon mu ile gbe n a won ni ariwa Africa ti bere si pa ara nitori ala ile ti nwon nj o wo ara won. Ogun adaja na po tobege ti awon Ijoba ilu Afrika miran fi ranse si awon mejeji wipe ki nwon dawo ija na duro titi awon yio fi ba won da sii.

A gbo wipe oro ija na ti wa nile tipe : awon kan ni awon ara ilu Somalia ni nwon ko nfiran, nwon ni awon ni nwon ngba ile ara Itopia diedie mo ti nwon.

Awon kan ni gbogbo ibi ti nwon gbe pa ala si ni Igberiko ni awon ara ilu na ngba mo ti won.

Awon ara ilu Somali paapa ni awon ara ilu Itopia ni nwon nwo ala ile ti awon lona ti ko to.

Awon Olori ilu Afrika miran ti nwon fe ba won pari oro na ni o dabi enipe nwon fe doju ti awon lodo awon Oyinbo alawo funfun ni oro na je.

# Ominira Nigeria

(O bere leju iwe kejo)

O mu Ibo ni 'la Orun;
O pa won po mo Hausa Oke Odo Oya;
O f' ewiri ogbon alumokoroyin;
Fin 'na ro orile ede Nigeria titun
Bi 'gi ati 'tukun ba f'ara won po;
L'o ndi 'gbo;
B' odo ati abata ba p'ara won po;
L'o nd' okun, d'osa:
T'o bo le a ye lara bi aso,
Tani yio ba mi sipe,
F' Awolowo ati Balewa,
F'Akintola ati Okpara
F'Azikiwe ati Saudana
Ki nwon pa imo po,
Ki Nigeria ba le di'le olori re.

Ojo kini ti osu October ni odun 1960 je akoko ti a ma se iranti re lailai ninu itan Ile Nigeria; ati nitoripe ni ojo yi ni Ijoba Gesi fun wa ni eto lati ma se eto Ijoba wa fun ara wa. Ayo ti gbigba anfani lati ma se eto ijoba ile wa fun ara wa yini a npe ni Ajoyo ti ominia ti ile Nigeria ni Odun 1960.

Ki a to le mo iyi ati itobi ti ajoyo ominira yi, a ni lati le so die ninu itan bi ominira na ti se de. Ni 'won nkan bi adojo odun ki o to di akoko ominira yi ni Ile ti a npe ni Ligeria bo si abe itoju awon egbe onisowo lati Ile Gesi. awon egbe onisowo wonyi ama ba ara won jowu nipa tita ohun ti nwon mu wa lati ilu Oyinbo fun tita ni ile wa, bakanna ni nwon isi ma ba ara won sure ije nipa rira pelu ti o fi je pe nkan ti enikan ba ra ni sile marun elomiran le raa ni sile meje abo. Eyi yi mu ki okunrin ologbon onisowo kan ti a npe ni Sir George Goldie pe gbogbo awon egbe Onisowo wonyi po ni odun 1879 o si ba won damoran pe o ye ki awon pa gbogbo egbe isowo won po lati le ma ra ati ki nwon si le ma ta ni iye kanna.

Awon egbe onisowo wonyi pa egbe won po, nwon si npe orupo egbe won yi ni Niger Company. Ki egbe yi ba ma dabobo ise owo won, ati agbegbe ti awon gbe nse ise owo won, nwon gba iwe ase lati odo Obabirin Ile Gesi ti a npe ni Victoria ni odun 1886.

(Iyoku di ose to mbo)




**E Polowo Oja Yin Sinu Iwe Irohin Eleti–Ofe losose ti o kunfun irohin didun**

## Your Radio Next Week

# Programmes For West Africa A Man, A Guiter, And A Bus

It is often thought that there is little chance to-day for the individualist among the teaming millions of a vast city like London, but there is a character there called Calypso Sam who provos that this theory is wrong. His story was told in a BBC African Service programme by Andrew Salkey, the novelist who said:

"Calypso Sam is a singer with a definite plan. He once told me: 'I am one entertainer with a difference When I sing I like to know that my message reaches out to the whole wide world. If I sing in night-club, I can only get my song across to a limited audience. So I prefer to sing on the top of those nice red London buses. I can capture thousands like that."

Salkey went on to describe Calypso Sam's plan, which was both methodical and professional. He always chose his bus route carefully–the busier the better. He sat at the back of the top deck and then played his guiter and sang for all he was worth.

Sam may have exaggerated his account to make a better story but he would explain. "Man, this London is the last remaining paradise for rugged individualists like me. You take a tip from Speakers' Corner in Hyde Park and you can't go wrong in London. In fact, you never reache the top in Britain in any activity uutil you learn to go out on a limb, express yourself loud and clear and stick to your plan mad as it may be."

## The Art Of Finding Out

Some people are good at memorising facts; others are good at finding out facts when they are needed. Which of these two facilities is most likely to lead to success ? Suzanne Cronje, speaking in the BBC African Service programme FOR PARENTS AND TEACHERS, thought that a retentive memory, though very useful, was less important than the ability to collect and make use of information.

Miss Cronje illustrated her argument by telling BBC listeners the true story of the university lecture who was asked by a student for an unusual piece of information.

He replied that he was not sure about that particular point but would supply the answer the following day. Tee student, who was neither modest nor wise, turned away with a contemptuous smile and remarked quite audibly that if those who were paid to instruct him were themselves lacking in education, he was wasting his time.

The lecturer called him back and said: 'Young man, you wish to ascertain a fact, but you went about it the wrong way. You asked me, although I was unable to enlighten you, which proves that you don't know how to acquire information.

Tomorrow, I shall possess the information bec–ause I know where to look for facts. The difference between your approach and mine is the difference between ignorance and education."

## BBC Next Week

During the coming week programmes in the BBC African Service after the NEWS at 12 0' clock (local time) on 17. 81 and 21. 615 megacycles in the 16 and 13 metre bands, will be as follows:

| | |
|---|---|
| Sunday, February 23 | London Fanfare |
| Monday, February 24 | A Book For Today, Focus On Africa, Around The Town With Sherman Browa, For You At Home |
| Tuesday, February 25 | A Book For Today, Post-mark Africa, African Mirror, Calling Ghana |
| Wednesday, February 26 | A Book For Today, Focus On Africa, African Forum |
| Thursday, February 27 | A Book For Today, Focus On Africa Discussion, Calling Nigeria |
| Friday, February 28 | A Book For Today, Focus On Africa. New Horizons, Writers' Club |
| Saturday, February 29 | Showtime, For Parents And Teachers, Calling Sierra Leone |



## European Champion To Captain Britain's Olympic Athletic Team

Robbie Brightwell, 23 year-old physical training teacher at the Tiffin Grammar School Kingston-on-Thames, London, has been appointed captain of Britain's athletic team for the 1964 Olympic Games in Japan.

Seen working with a class in the school gymnasium, Brightwell is the European 400 metres champion and one of Britain's most consistent performers.


# Read And Advertise In Eleti-Ofe

## Ejo Kotemilorun Awo Ku Ferefe Ni Kotu

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Ninu ejo ti Oloye Awolọwọ pe, ọna mẹrin le ọgbọn ni o fi se alaye wipe Adajọ Sowemimo fi ṣi a rẹ lọna. Ọkan ninu awọn lọya amofin ilu Oyinbo ti orukọ rẹ njẹ Victor Durand ni Oloye Awolọwọ gba, a gbọ wipe lọya na si ti kọwe si adajọ-agba Ọgla Adetokunbọ Ademola wipe ki nwọn fun on laye lati le wa si Nigeria wa se ejọ na.

A tun gbọ wipe awọn enia marun miran, awọn Ayọ Akinsanya, L. K. Jakande, J. O. S. T. Ọrẹdẹin ati Simeon Oyeshile pe ejọ kotemilorun si kotugaaran.

---

AYILUKA NI:

(O bẹrẹ loju ewe Kinni)

ni Olowogbowo l'Eko, ti nwọn si nfẹ tu wọn ka nisisiyi.

Ọrọ na wa di o de ọnu akayin akara wa di egungun. Awọn Ijọba ni ile ati adugbo ko si ni ile ati adugbo ko si ni Okun Alasia mọ ti awọn yio ru awọn ara Olowogbowo gba. O ṣe ki nwọn ba wọn wa adugbo miran l'Okun ti awọn yio pejọ si tabi ni ti awọn ara Oko Awo ni nwọn fẹ ṣe ọrọ won? Ara Olowogbowo ọrọ re o!

Ka Oro Ayiluka ni oju ewe karun

## Dokita Chike Obi Foro Oselu Sile Patapata

(O bẹrẹ loju ewe kẹji)

Ọdun mẹta gbako ni a gbọ wipe Ọgbẹni Obi bere lọdọ awọn Ọla l'ewe rẹ ni Ibadan wipe ki nwọn fi fun on laye ki on le fi ba wọn ṣe ọrọ ilu wọ; gbogbo igba ti o ṣe nile Igbimọ awọn aṣofin ni o ma ibe gbona nitoripe Chike Obi ko gba gbẹrẹ, orişirişi aşiri nkan ni o nlu.

Nwọn fi igba kan yọ ọ nile ajọ igbimọ na şugbọn o pejọ, ẹjọ rẹ jare, o tun di ọmọ ile igbimọ pada.

O wa ninu awọn ti nwọn mu, ti nwọn mba şe ejọ Ọtẹ nigbati nwọn mu awọn Oloye Awolọwọ wipe nwọn ditẹ si Ijọba şugbọn adajọ Showẹmimo ju u silẹ pẹlu awọn miran.

Chike Obi ni ọrọ omugọ ni awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (NPC) nsọ ni Kaduna wipe ọwọ awọn si ecku ida Ijọba yio wa titi lailai. Dokita na tun şe alaye wipe ko yẹ ki awọn alamojuto Ijọba ma yọ awọn olukọni ti awọn nşişẹ ni ile ẹkọ giga unifasiti. O ni yiyọ ti nwọn yọ Omọwe Oyenuga ni ni Unifasiti Ife ko ba oju mu rara.

## Ijoba Pa Titi 'Awolowo' Loruko Da

IBADAN... Irohin kan ti a mu gbọ lati ọdọ awọn alamojuto Ijọ a Ipinlẹ Iwọ Orun ni ijẹta n ti awọn opopo kan ti nwọn ti fi igba kan sọ ni orukọ awọn diẹ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ (AG) bi Awolọwọ, Rotimi Williams, Adegbenro, Enahoro ati Ọdẹbiyi, ti nwọn paşẹ wipe ki nwọn yi awọn orukọ na pada si omiran.

Popo ti nwọn ti fi igba kan sọ ni orukọ Awolọwọ ni a gbọ wipe nwọn ti yi pada si orukọ Bişọbu Oyelọde; ti Alh ji Adegbenro di orukọ Adajọ Adetokunbọ Ademola; Rotimi Williams di Balogun Apanpa; ti Oloye Enahoro ati Olu J. O. Ọdẹbiyi paapa ti gba suna miran.

Ko ye wa si nkan ti o fa iyi orukọ pada na şugbọn nwọn ni aşẹ na lati ọdọ awọn alaşẹ Ijọba ni o ti wa ni Agodi kişe Oke Mapo rara.




Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street Lagos
Phone 23340 Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 467.